# ELETI OFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 871 SATURDAY JUNE 1st — JUNE 7th 1963 KỌBỌ MEJI (2D)


# Alhaji Adegbenro Jare Apakan

EKO—Ọrọ ẹjọ Kotu Ko-tẹmilọrun ti Alhaji D. S. Adegbenro tiṣe Balogun ẹgbẹ Afẹnifẹre fi igba kan gbe lọ si ilu Oyinbo, ti awọn oguna gbongbo adajọ ilu Ọba na da a 'are koi ti dopin nitoripe nwọn ko sọ ẹniti o tọsi gan lati jẹ Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun Nigeria ninu iwe idajọ wọn.

Gẹgẹbi ọrọ ẹjọ na ti nwọn da ni ọjọ Aje ti o kọja lọ yi; Oloye S L Akintọla tiṣe Olotu Ipinlẹ na ni o fi igba kan pẹjọ wipe yiyọ ti Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Nigeria, Ọlọla Adesọji Aderemi yọ on kuro lori aga ninu ọdun to kọja ko tọna rara, adajọ kotu-gantan Ibadan si da a lare.

## Iya Kan Sin Omo Re Laye

ABAKALIKI-Ọmọge kan, Benedicta Ike, ọmọ ọdun mejid'logun, ọmọ ile Iwe awọn Aguda ni a gbọ wipe o sin ọmọ ọjọ mọkanla ti o bi loye n itoripe ọmọ rẹ na ko ni baba ni baba.

(Wo yoku loju ewe kejọ)

## Oloye Akintola Je Olori Are

Koko nla kan ti o wa ku niun ọrọ ofin ẹjọ na ni ti wọn ko fọ mọlẹ ni pe bi Gomina yi lagbara rara lati yọ Olotu Ijọba kuro ni nu iṣẹ rẹ lai jẹ wipe nwọn lọ fọrọ na han ninu ile igbimọ awọn Aṣofin ki nwọn sọ ṣako wipe awọn ko ni igbẹkẹle ninu iṣẹ rẹ mọ.

(Wo iyoku loju ewe kejọ)

## Baba Aganyin Kan Jalaisi Lojo Tojoye

SOKOTO—Baba Aganyin kan ti o ti de ilu Hausa nibi nigba ogun naminalẹ, ti orukọ rẹ njẹ Charles Edward Bruce, ẹni ọdun mọkanleladọrin, ni a gbọ pe o pade agbako iku jamba mọto lọjọ ti nwọn ṣe ẹyẹ oye kan ti Ọba ilu Oyinbo gbe fun un.

O di ọdun mẹrinleladọta nisisiyi ti Ogbẹni na ti wa si ilu Hausa, o si wa ninu awọn ti nwọn kọ fi ẹsẹ jagbo de Oke Ọya, iṣẹ ijọba a nfiun wọn ni iwe-aṣẹ oju ọna-mọto ni o si nṣe nibiti nwọn gbe npe agbegbe rẹ ni Sardauna nisisiyi.

O ti pẹ lẹnu iṣẹ ijọba ti o ti nṣe yi tobẹgẹ ti nwọn fi rohin re fun Ọba ilu Oyinbo wipe o yẹ ki o fi oye kan daa lọla; Ọba na si ṣe bẹ. Ewe-Oye na ni o lọ gba pẹlu ẹyẹ 'lọdọ Gomina ni Kaduna ki o to pade agbako iku mọto lọna nigbati o npada lọ si Nubi, ibi ti o ngbe nilẹ Hausa nisisiyi.

## Olosa Gba Eru Awon "Dieyin" L'ona Onitsha

ONITSHA — Oku adiẹ ko mọ ẹniti ọ sin on ni ọrọ awọn janduku ọlọṣa onibọn ajiyin ti nwọn da awọn oniṣowo ti ẹ ma npe ni "Dieyin" lọna lọna Onitsha si Ẹnugu ti nwọn yinbọn si nwọn, ti nwọn si gba gbogbo nkan tita ti u wọn fẹ ko wọlu Ẹnugu.

Bayi ni a gbọ irohin na si lati ọdọ akọwe onirohin wa ti o fi waya irohin na ṣọwọ si wa ni ana. O ni ni alẹ ijẹta ni nkan na ṣẹlẹ ni gẹrẹ ti awọn oniṣowo Dieyin yi ti bọ si odi ilu Onitsha tan.

Nwọn ni bimọto akẹru ti nwọn ko awọn ọja si ti de awọn buso mali marun ni dẹrẹba mọto akẹru na ṣe akiyesi wipe igi nla kan yi sọna, o si da mọto rẹ duro pẹlu mọto awọn kan ti o tẹle e lẹhin.

(Wo iyoku loju ewe keji)

## Ategun Buruku Pa Awon Ara India

CHITTAGONG BENGAL — Atẹgun alanjannu kan kọlu ilu awọn Imale India ni ijẹta, o pa ẹgbẹdọgbọn (5,000) ẹnia ninu wọn. Oniiko obute ilu ti atẹgun buruku na kọ gba njẹ Chittagong mọ gbogbo ilu ti o wa lebute Bengal, o si tun wo gbogbo ile wọn lulẹ.

Gomina ilu na ni awọn ko ti le sọ iye ẹnia ti atẹgun na pa bọya o ju ẹgbaje enia (14,000) ti ti ọdun keji pa lọ, ile ti o ba jẹ ko ni ye. Ojiji ni atẹgun na bẹrẹ ni ijẹta.

(Wo yoku loju ewe kejọ)

## Loya Igbomina Kinni Di Omo Egbe Olomi (NPC)

EKO—O jẹ iyanu fun gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ Olomi (NPC Youth Wing) ẹka agbegbe Ilorin ti nwọn wa l'Ẹko lati ri Ọgbẹni J. A. Oyeyi, ọmọ Oro ti o kọ di loya ni ipade wọn ti nwọn ṣe ninu ile baba ẹgbẹ wọn ni Oko-Awo laipẹ yi, ti o si sọ fun nwọn wipe ẹgbẹ oṣelu ti wọn ni on yio ṣe.

Gbara ti o kọ wọle, akọwe awọn ọmọ ẹgbẹ na, Ọgbẹni J. O. Kolawọle ti o wa lati Ilorin ni o kẹ kii ku abọ, o ni fi loya (lawyer) ọmọ Oro na, ti o kọ jẹ ẹnikini ti yio kọ di loya larin awọn ara ilu Igbomina kaat gbogbo awọn ti o wa si ipade na, gbogbo wọn si gbaa tọwọ tẹsẹ pẹlu baba ẹgbẹ wọn, Ọgbẹni Raphel Shorun Babaoye.

Loya Oyeyi paapa ninu ọrọ rẹ, o ni on dupẹ fun wọn fun ẹyẹ gbigba ti nwọn ṣe fun on lọjọ na, o ni nkan ti o jẹ ki on ṣe ipinnu lọkan na wipe ti awọn ẹgbẹ Olomi (NPC) yi ni on yio ṣe ni ti irohin

(Wo yoku loju ewe kejọ)

# Baba Alagbede Ibon Wo Gawu Ni Ihiala

ẸNUGU—Ọwọ ọlọpa ti tẹ Ọgbẹni kan ti nwọn ni on ni o nrọ ibọn-llewọ fun awọn ọlọṣa ni Ipinlẹ Ila Orun. Orukọ ti ọkunrin na njẹ nwọn ni awọn ko ni ti sọ fun onirohin Eleti Ọfẹ ti o sare dẹ ibi iṣẹ awọn ọlọpa lati gba irohin na ni ẹ gbadun.

Irohin ti a gbọ ni pe ni abule kan ti nwọn npe ni Ihiala leti Onitsha ni awọn ọlọpa ti ri ọkunrin na mu nibiti o gbe nrọ ibọn. Awọn ibọn ti o ti rọ ti nwọn ba lọwọ rẹ rlọ bi irinwo.

Awọn enia meji ni nwọn ba lọdọ baba alagbẹdẹ ibọn na, ti nwọn nran an dọwọ ninu iyara ti o ti nrọ awọn ibọn na, gbogbo wọn ni nwọn si wa lọ si teṣan ọlọpa ni Onitsha ki nwọn to ko ẹru ibọn ati ọta wa si Ẹnugu lana.

Baba alagbẹdẹ ibọn na ti ri ṣe pupọ nitori awọn ọlọpa ri owo to igba ponun ninu owo ti o ti pa lori ibọn ti o ta fun awọn ọlọṣa ti nwọn nfi ibọn ko ile onile kiri.

## Olosa Da Awon Onisowo 'Dieyin' Lona

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Bi nwọn ti da mọto wọn nadu-ro ti nwọn nro e iti nwọn yio se ni pa ig ti o yi sọna na, ni awọn ogbologbo ọlọṣa yi ba sare jade nibiti nwọn g e ti sapọmọ ninu igbo. Gbogbo awọn ole na ni nwọn fi nkan boju bamu bamu. Nwọn ni ki awọn oniṣowo nwọn-yi "ju tọwọ wọn silẹ", awọn yẹn kọ.

Nigbati nwọn ri pe awọn oni-ṣowa yi lẹ ṣe akọ ni nwọn ba fa ibọn ilewọ pẹlu ada ti nwọn so mọra jangbọn jangbọn yọ ti nwọn bẹrẹsi ṣa wọn bi ẹnisagi.

Gbogbo ẹru bi oni nkan bi ẹgbẹdọgbọn ponun (£5,000) ni nwọn ri ji gbe.

Gbogbo awọn onisowo na ti nwọn gba ọgbẹ ni awọn ọlọpa ti ko lọ si ile awọn alamodi ni ilu Onitsha.

## How British Liv[e] Northern

LONDON — Ten Northe[rn] ... from London yesterday ... six-week visit to Britain ... Council.

The group, which in[c] ... teachers, left for a ten-da[y] ... Southampton in which ... ment, education and child ... trip will be devoted to ... particularly women-live a[nd] ... will be visiting schools, ... mens's voluntary societie[s] ... be visiting the women's ...

The tour takes the ... through England to Sco[t]land and ends with sight-seeing visits around Lon-don.

In the party are Mala-ma Habiba Kaile, wife ... the Northern Minister ...



**Iwọ ha nwá asiki funra rẹ bi?**

**Ki yio pẹ lọ titi fun ọ bi o ba nfi owo pamọ**

**latigba dẽgba nile ipamọ owo ti Barclays**

Owo rẹ mbẹ labẹ abo lọwọ Barclays. Ki yio sọnu atipe bi o ti npọ nĩbọ ni bẹni yio ma lési. Lọ bère nibiṣẹ Barclays tombẹ nitosi ọdọ rẹ nipa fifi owo pamọ ki o si bẹrẹ lati ṣe bẹ ni kiakia.

"BI IWỌ ... ASIKI F...



Awon Iwe Asiko :-

# Awon Ole Obi Pa Omo Won

Ninu Iwe ALUFA ATILADE

Bi a ba sọ oko s'ọja, ara ile ẹni ni ba. Totọ. ọṣe bi owe o.. Ni igba laelae, awọn idile kan t'ọkọ t'aya wa ni ilu kan. Awọn enia yi ki ṣe ọlọrọ, ṣugbọn Ọlọrun ko fi onjẹ ọjọ pọn wọn l'oju.

Ohun kan ṣoṣo ti o jẹ ẹdun ọkọ ati aya yi ni pe ọmọ kan ṣoso ti nwọn ni ni ode aiye ti lọ si ẹhin odi fuu ọpọlọpọ ọdun. Nigbati o se, nwọn ko tile gburo ọmọkunrin na mọ. Eyi yi wa di orisun ibanujẹ wọn nipa ero pe bi ọjọ iku ba de, awọn ko ni ri ọmọ lati sin oku wọn.

## Lati Owo AKOWE

Ni gbogbo akoko yi, ọmọ wọn yi ti kọ iṣẹ alagbẹdẹ golu ni ibalẹ, o ti sise, o si di olowo. Ọmọ yi ti, o ti fi ile silẹ ni'gba kekere ko gbagbe awọn obi rẹ rara, on papa ndaniyan lati ri awọn obi rẹ, gẹgẹbi awọn obi rẹ, papa nti nfo'ju s'ọna lati ri i.

Nigbati ọwọ ọmọkunrin yi ti tẹ nkan ti o nwa, o pinnu lati pada lọ si ilu rẹ. Nitoripe owo rẹ ti di pupọ yanturu, ọpọlọpọ alaru ni o gba lati ru awọn apoti aṣọ rẹ, apoti owo rẹ, apoti irin iṣẹ rẹ ati apoti ohun elo bi awo oriṣiriṣi ati ọbẹ ati agunje ati ṣibi oriṣiriṣi ati oniruru ohun faji miran ti a ko le ma ka l'ẹsẹsẹ.

(Wo yoku loju ewe kefa)

## Adajo Ni Ki Nwon Pa Awon Egun Onifayawo

ABẸOKUTA — Adajọ-agba Kotu-gianran, Ọgbẹni Wm Travers Charles ṣe idajọ lori awọn Egun ara ilu Badagry mẹta onifayawọ ti orukọ wọn njẹ Modonu Ejimode, Jide Dipehin ati Honfu Nweh ti nwọn pa ọkunrin awakọ kan ti o njẹ Noah Agẹmọ lọjọ omi lọdun ti o kọja; o ni ki nwọn pa awọn na pelu.

Nwọn ti bẹrẹsi to ẹjọ wọn na tipẹ ṣugbọn eyi ti o jẹ pato ninu ẹjọ ti nwọn ro mọ awọn ọkunrin Egun apania na niyi.

Awọn ọlọpa ni, o di ọdun kan gbako nisisiyi ti awọn ọkunri onifayawọ yi pade Agẹmọ loju omi ninu ọkọ ti o nwa lati fi ko ọja ẹru ti o ra sọda ninu odo ọsa leti abule kan ti nwọn npe ni Shoke.

Oju wọn yanyan bi nwọn ti foju kan ẹru aṣọ aran oriṣiriṣi ti awakọ na di sinu ọkọ rẹ, nwọn ni ki o da ọkọ rẹ na duro. Bi o ti da a duro ni gbogbo wọn ba bọ sinu rẹ.

Nwọn ni o ku ọna ti yio gba nitoripe, aṣọbọde ni awọn; ko si sise, ko si aiṣe, awọn ni lati mu u on ati gbogbo ẹru rẹ lọ si ọdọ ọga awọn ni. Were wọn ti gba ọpa-ajẹ lọwọ rẹ ni nwọn ba ṣa ọkunrin na pa. Nwọn sọ oku rẹ sinu odo ọsa.

Awọn na ko mọ wipe gbogbo nkan buruku ti awọn nṣe yi ni awọn kan ti nwọn wa ninu igbo leti ibẹ nri. Awọn enia na ni wọn lọ sọ gbogbo nkan yi fun awọn ọlọpa ki nwọn to mu wọn.

# Okunrin T'o Pa Iyawo Re Gbojo 'Ku

GBỌKỌ — Ọkunrin agbẹ ọmọ Tiv kan ti o njẹ Atsaka Akayougo ti o pa iyawo rẹ ni adajọ-agba, Ọgbẹni J.P Smith ti o ṣe adajọ ni Kotu Ipinlẹ Ijọba Ariwa ni ilẹ awọn Hausa ni ki nwọn lọ yẹgi fun nitoripe o jẹbi pipa ti o pa iyawo rẹ.

Awọn ọlọpa ni Nguveme Akayougo ni orukọ iyawo re ti o pa na njẹ. Awọn ọlọpa ni ninu oṣu Keresimesi ti nwọ se lọ yi ni agbẹ na ti ni ki ẹlu iyawo rẹ ṣe gbolohun aṣọ, ija na pọ to bẹ ge ti o yọ ọwọ yi fi ti lo ti pẹlu ẹru rẹ mọ, o si ku lọ sọdọ iya (iyawo) rẹ.

Ẹlẹri kan ti orukọ rẹ njẹ B.Belgoro ni oju on ni ọrọ na ṣe nigbati ọdaran yi wa si ile iya iyawo lọjọ kejì, o ni on wa wo iyawo on, ṣugbọn nigbati o wọ ọdẹdẹ wọn, o na okunrin kan ti o mb ya rẹ si o.

Eyi ti a ki a bii, ni o ba wo kunma, ti o bẹrẹsi ke bo iyawo na, o bẹrẹsi ti o fi pa a sibẹ.

## Awon Omo Olympio Mbo Wa Si Nigeria

LOME—Akọbi ọmọ Dokita Olympio Olotu ilu Togo ti awọn ọlọtẹ kan lu pa ni odun yi ni gbogbo awọn ẹbi ẹn ti fohun sọkan wipe ilẹ Nigeria ni awọn yio ko wa lati ma gbe di ọjọ ku awọn.

Bonito Olympio ni orukọ akọbi ọmọ olotu na njẹ, o si ni awọn aburo, mẹta wa ninu wọn ni ilu Oyinbo ti nwọn nko eko lọwọ nisisiyi. Ọkan ninu wọn ti o nṣe Gil nwa fun isinmi ni aipẹ yi, ilu Eko ni o gbe lo gbogbo rẹ.

Ọgbeni Benito ni iro ni nwọn npa ti nwọn nsọ wipe gbogbo ilu ti fọkan balẹ ni Togo, ko si ọtẹ mọ. O ni gbogbo ara gbogbo ti nwọn nfẹ lo, lori awọn ti nwọn fẹ ti baba on ti nwọn ti lu pa ni nwọn fe lo o si.

**Plushes, Velvet Velveteen, Damask & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Mosre Street, (Faji Market)

LAGOS NIGERIA.

The House Where Economy & Satisfaction are Guaranteed.

# ELETI–OFE

NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMS

28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL XIV. NO, 871 SATURDY JUNE 1st — JUNE 7th 1963


ỌRỌ OLOTU

## Awon Obinrin Wa Pegede

Ki a maṣe si tu ete, ipade ajọ awọn obinrin Apapọṣe ilẹ Nigeria ti nwọn ṣe l'Eko ni ijẹjọ kuro ni yẹyẹ awọn obinrin na pegede, nwọn tun fi gbọọrọ jẹka fun ipin u orişirişi ti o mu ọgbọn lọwọ ti nwọn ṣe ninu ipade na.

Gbogbo ipinnu ti nwọn ṣe ni ipade na dun mọ awa Eleti-Ọfẹ ninu pupọ tobẹ gẹ ti a fi fi oju ewe iwe Olotu wa sile ninu ọsẹ yi lati kan saara si wọn.

Ko si ẹniti ko mọ wipe awọn obinrin nwọnyi ni ori lọdọ ọkọ wọn; bẹ bi ori ba bajẹ gbogbo ara lo bajẹ.

Ni igba aiye atijọ ipo ẹru ni a ka awọn obinrin ko ba jẹ alawọ dudu ni tabi Oyinbo Alawọfunfun ni ṣugbọn nisisiyi aiye yi ti yi pade, gbogbo nkan ti awọn ọkunrin nṣe ni awọn obinrin paapa nṣe.

A gbọ wipe nwọn ṣe ipinnu wipe awọn ko fẹ ki awọn obi gba owo-idana lori awọn ọmọbinrin wọn mọ nitoripe owo-idana na nsọ awọn obinrin dẹru. Nitotọ ni ọrọ yi nitoripe aṣa owo-idana le pupọ lọdọ awọn ara wa ni iha Ipinlẹ Ila Orun tobẹgẹ ti o fi jẹ wipe awọn obi ni ilu Ibo ma ngbadura nigbagbogbo wipe ki Ọlọrun fun awọn ni ọmọbinrin jaburata nitoripe oko koko (cocoa) awọn niyẹn.

Awọn obi miran ngba nkan bi irinwo pọnun (£400) tabi ju bẹ lọ lori ọmọbinrin kan. Iru iwa bayi ni ko njẹ ki awọn ọmọ wọn obinrin ri ọkọ ti yio fẹ wọn sile, iyẹn na lo si jẹki nwọn fi IWA AGBERE ṣe iṣẹ.

Iru ajọ ipade ti awọn IYA WA nwọnyi ṣe yi dara pupọ, o si jẹ nkan ti o le ṣe wa ni anfani kẹgẹbi erile-ede, ṣugbọn ko da wa loju wipe awọn AUNTI ẸLẸYINJU ẸGẸ ti nwọn wa lode nisisiyi mọ wipe awọn kan wa ninn awọn obinrin ti nwọn ṣe ipade bi aiye awọn yio ti ṣe dara lọla fun wọn nitorina a da ni imọran ki awọn Olori ẹgbẹ obinrin nwọnyi maṣe gbagbe lati pe awọn ọmọge wa sibẹ nigbamiran ti nwọn ba tun jẹ ṣe iru ajọ ipade ti o nmu anfani wa bayi,

A gba fun yin, ẹnyin iya wa.

## A Ki Kenyatta Ku Orire

Irohin kan ti a gbọ nipa idibo ti nwọn di ni ilu Kenya laipẹ yi ti awọn onirohin agbaiye ni awọn ọmọ ẹgbẹ oṣe u kan ti nwọn npe orukọ wọn ni KENYA AFRICAN NATIONAL UNION (KANU) ti Ọgbẹni Jomo Kenyatta nṣe olori wọn ni o bori, ni o nu wa lọkan lati ki olori ẹgbẹ na ati awọn ọmọlẹhin rẹ wipe nwọn ku orire, nwọn si ku ajabọ.

## Iwe Si Olotu

## Agbako Moto Lona Lalupon

IWO — Awọn obinrin meji kan ti orukọ wọn nje Iyabọ Banjọ ati Cecilia Seiba pade fagbako iku mọto lọna Lalupọn ninu ọsẹ yi nigbati nwọn nlọ si ọja ni eti abule wọn ni Ejioku.

Ni ọjọ ti ijamba na ṣe awọn obinrin mejeji yi ọja ni nwọn sọ wipe awọn nlọ ṣugbọn bi nwọn ti tinrin lọ ni nwọn ṣe akiyesi awọn moto bọlẹkaja meji ti nwọn nsare le ara wọn lati gba ọna lọwọ ara wọn.

Ere na pọ to bẹ gẹ ti gbogbo awọn mọto mejeji na fi sare kuro loju titi, ti nwọn inu igbo lọ ba awọn obinrin na nibiti nwọn gbe ya si, ti nwọn si lọ kọlu wọn ti ọkan si lọ kọlu wọn ti ọkan si pa wọn sibẹ

ỌRỌ OLOTU

Boya a le ri ninu ẹnyin ọkawe wa ti ko mọ nkankan nipa ọrọ ilu ti nwọn npe ni Kenya ati wipe nibọ ni ilu na gbe tilẹ wa; ilu Oyinbo ni tabi ilu awọn Larubawa ni.

Aladugbọ ni a jẹ ni Afrika pẹlu awọnara ilu Kenya, awọn wa ni apa ila Orun awa ara Nigeria. Ilu wọn jẹ ilu ti o tu ni lara pupọ, eyi si jẹ ki ogunlọgọ awọn Oyinbo alawọfunfun fi ibẹ ṣe ile; nwọn gba ilẹ lọwọ awọn ọmọ onilẹ fun ọpọlọpọ ọdun ti nwọn fi wa wa labẹ Ijọba Gẹsi.

Iya yi pọ tobẹgẹ ti Ọgbẹni Jọmọ Kenyatta ti o di Olotu ilu Kenya loni fi ọpọlọpọ ọdun sa agbara. lọsan ati loru, ti ko sun ti ko wo, ti o nwa bi on yio ṣe yọ awọn enia rẹ loko ẹru.

Ijọba ilu na fi igba kan muu pẹlu awọn ọmọlẹhin rẹ wipe nwọn da ẸGBẸ ỌLỌTẸ kan silẹ ti nwọn npe ni MAU MAU, nwọn ju sẹwọn ọdun meje; ọdun marun abọ ni o ṣe lọgba ẹwọn ki nwọn to da a silẹ.

Ṣe ẹnyin na wa ri nisisiyi wipe oju ẹniti o ba fẹ ko ori-tutu ati ori-gbigbẹ jọ ni lati ri nkan? Ọrọ oṣelu kişe yẹye rara.

Ọgbẹni Kenyatta, a bọ ọ pupọ pe nisisiyi ọwọ ti tẹ ẹku-ada agbara ti de ọwọ rẹ ki o jọwọ ki o maṣe şii lo, ki o gbagbe iya ti ijọsi ti awọn alawọfunfun ti fi jẹ ọ ati awọn ara ilu rẹ; ki o ṣe Ijọba tuntun ilu Kenya ni Ijọba ir run fun talaka ati olowo.

Nitotọ bi ọdẹ ba ro iya ti on jẹ ninu igbo bi o ba pa ẹran tan ko ni fun enia kan jẹ.

Ọgbẹni Jomo Kenyatta, a ki ọ, o ku orire.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

### Lati Owo yiluka

## Owo-Dana

Enyin ara mi, ipade ti awọn obinrin wa ṣe l'Eko ninu ọsẹ ti o kọja wu mi pupọ fun awọn ipinnu nlanla kan ti nwọn ṣe. Ekinni, nwọn ni awọn fẹ ki Ijọba ṣe ofin wipe ki awọn obi ye gba owo BABA—GBỌ, IYA-GBỌ lọwọ ẹniti o ba fẹ fẹ ọmọ wọn.

Ọrọ na dara pupọ, ṣugbọn loju awọn ara mi ni ilu awọn IBO, o dabi ẹni wipe awọn ọmọ egbẹ obinrin nwọnyi fẹ gba ijẹ lẹnu awọn iya Hanah ati iya Maria ti nwọn mbẹ ni Ipinlẹ Ila Orun mo mọ nkankan daju, nkan na ni wipe owo-idana ko le parẹ ni ilu Ibo lailai.

## Oko Koko (Cocoa)

Nwọn ko ni oko-Koko (cocoa) ni ipinlẹ na to bẹ, ọdọdun si ni awọn obi ma ngbadura wipe ki awọn bi ọmọbinrin jaburata, ki awọn le ri owo-idana gba lori wọn. Ọmọge ta ju koko lọ ni ilu Ibo, owo iyagbọ ati babagbọ bẹrẹ lati igba ponun de ẹgbẹta ponun.

Eleyi lo jẹ ki awọn ILE'MOṢU obinrin pọ lọdọ awọn ara wa, Bi o ba fẹ rao bi awọn obinrin ti ko lọkọ ti ni 'ilu Ibo ki o lọ si Pọta (Port Harcourt), ki o tun gba Owerri lọ, ki o lọ si Ẹnugu, awọn ti Aba pẹlu ti Onisha wa nibẹ.

## Tiro—Ete

Awọn obinrin ti ko lọ si ile ọkọ yi. pọ pupọju awọn ti o lọ si ile ọkọ lọ. Nwọn nti i'tu kan de ilu kan ni; bi o ba de Apapa Ajegunlẹ wa ba wọn, bi o ba lọ si Abule Ijẹsha l'Eko nwọn pọ nibẹ: nwọn tun kun Ekotẹdo ni Ibadan jaburata. Bi nwọn ti nkun oju ni atike; ni nwọn nle tiro-ẹnu John ko sọ wipe on ko fẹ iyawo, baba Hannah ni ko jẹ.

Ki a wa pada sọdọ awọn A-KO-BORUN-LERI ilemoṣu ọmọ Yoruba: Ọrọ owo-idana ṣẹ nparẹ ni ilẹ yi, awọn obi ọmọ Yoruba ko gba owo idana ti — bẹ lori awọn ọmọ wọn, awọn ọmọ alara paapa ni o nta ara wọn fọkọ, ọpọlọpọ wọn ko si fẹ gbele mọ nitori gele onilẹgogoro ati bata UMIMIEJO ti nwọn

## Kof'orun

Nwọn ni bi a ba mbu ẹtu inu a ma run awo; awọn ẹgbẹ obinrin yi ni ki Ijọba jọwọ ko o ba awọn bẹ awọn olorin ti nwọn nkorin sinu awo rẹkọdu bu awọn obinrin pe ki nwọn ye kọ ọ mọ. Eleyi nikan ni emi Ayiluka ko faramọ nitoripe awọn iyawo ti ko le ponmi, ti ko le lọ ata, ti ko le se ọbẹ ọ nilu, bẹ si ni awọn aya KOF'ORUN ti nwọn nfi bebe pa ọmọde.

Emi Ayiluka ki Iyaafin Funmilayọ aya Ransome-Kuti ku agba. Ọmọ Lisabi, Edunare majẹ ki wahala rẹ jasan o. Ti ẹ ba tun fe ṣe iru ipade bayi, mo bẹ yin ki ẹ lọ ṣee ni Enugun ati ni Kaduna.

## Obinrin Oke Oya

Ọrọ Kaduna ti mo fẹnu kan yi ieki nniran ẹbẹ ti awọn ọmọ ẹgbẹ obinrin yi bẹ Olotu Iiọba Ipinlẹ Ariwa ni Oke Ọya, Ọlọla Sardauna Sokoto pe ko yọnda fun awọn obinrin ilu Hausa pe ki nwọn le ma dibo ki awọn obinrin Hausa papa le ma lẹnu ninu ọrọ ilu sisọ nilẹ yi.

Eleyi dun pupọ ṣugbọn o dabi ẹni wipe awọn alamojuto iṣẹ Ijọba ilẹ Hausa yi ni wipe awọn ko ti ni obinrin ti nwọn laju pupọ tobẹgẹ ni Oke Ọya. Nisisiyi enia mẹwa ni awọn obirrin ti nwọn ran lọ si ilu Oyinbo ni ana ode yi fun "ẹkọ ilaju." Nigbati ẹ ba nka iwe mi yi gbogbo wọn a ti gunlẹ ni London. oṣu mẹfa gbako ni nwọn yio ṣe nibi a nwo ilu kakiri.

## Omo Dara

Mo mọ wipe ti nwọn ba pada de awọn obinrin na a jọju diẹ, nwọn a si ba ara ile mu diẹ. Ọlọla Ahamadu Bello paapa ko fẹ ki awọn obinrin ilu on rẹhin, ọrọ awọn ẸLẸHA ti awọn ha sile ni o kanpa.

Gbogbo nkan ti nwi pada lọdọ awọn ọmọge ilu Hausa, awọn na ko fẹ ki nwọn ha wọn mole mọ. Mo gbọ wipe nwọn ti njijo omọdara-o-dẹjọ. nwọn si ngba ẹbun Miss Kaduna ati Miss Sokoto, awọn na si nkun ete ni laali.



## Iya Oni Moto

**Aworan yi ni igbati obinrni elere kan, Caron Gardner nfi moto alupupu tuntun kan ti nwon npe ni ARIEL LEADER ti nwon gbe wa si ibiti nwon se ibewo awon Moto ati alupupu tuntun ni Plackpool, England. Moto alupupu na ko e be.**

# Akiyesi

**Bi Oja ti O Nta ko ba lo daradara mase gbagbe lati se ipolowo re sinu iwe irohin Eleti-Ofe. Nwon nka a kakiri Oke-Okun ati ni Nigeria Eleti-Ofe ti daraba,**

# Iwe Asiko

(... ewe kẹta)

Ni alẹ ni o wọ ilu ti awọn obi rẹ wa, ṣugbọn ko mọ ile wọn. O bere awọn obi rẹ lọwọ ọpọlọpọ enia, ṣugbọn ko si ẹniti o le ranti iru apejuwe ti on nṣe nipa ara rẹ ati ti awọn obi rẹ. Nigbati o di awọlepa ara rẹ ... awọn obi rẹ. Nigbati o di awọlesen ni o ba ọkunrin kan ti o joko ni ojude ilẹ rẹ. O sun mọ ọ, o si bẹrẹ si isọ itan ẹniti on iṣe fun u ati gbogbo wahala ti on ti ṣe ti on ko si le ri le ti ẹniti o le fi ile awọn obi rẹ han on. Inu on yio dun pupọ bi on ba le ri ẹniti o le sọ fun on bi awọn obi on ba ti kuro bi nwọn wa laye, bi nwọn ti kuro ni ilu yi tabi nwọn wa ni'lu.

Nigbati ọkunrin agbalagba yi ronu l'ori itan ti ọmọkunrin yi ti sọ fun u, o ranti pe awọn obi ọmọ yi ti sọ ọrọ na l'eti on ri. Nigbati o da a loju pe ọmọkunrin yi ni ọmọ awọn obi ti o wa si ọkan rẹ o pe ọkan ninu awọn iranṣẹ rẹ, o si sọ fun u pe ki o mu ọkunrin lọ wọ ninu ile kan ti aye wa ati pe nigbati o ba di owurọ on yio wa bẹ ẹ wo nibẹ.

Iranṣẹ yi mu alejo na ati awọn alaru rẹ lọ si ẹnu ọna ile na, o si kan ilẹkun. Nigbati nwọn ṣi ilẹkun, o sọ pe, ọga on lo ran on lati mu alejo yi wa si ọdọ wọn pe ki nwọn fun u ni aye lati sun di owurọ ọla.

(Iyoku di ọsẹ ti o mbọ)

# Oko Omi Tuntun



Awọran ọkọ jomi-joke ti awọn Ijọba Gẹsi ṣẹṣẹ ṣe ko niyi. Ọrọ abẹ omi ti yio ma wa ibiti ọkọ awọn ọta ba gbe wa kiri ni eleyi, owo n'a ni nwọn fi kọ ọ, o tobi ju ọkọ abẹ-omi na nje HMS DREADOUGHT, o si ... sare pupọ.

## Egbe Awon Obinrin Ni Awon Ko Fe Owo Idana Mo

EKO— Ninu ajọ ipade nla kan ti gbogbo Apapọṣe ọmọ Ẹgbẹ awọn obinrin ṣe l'Eko ninu ọsẹ ti o kọja ni awọn ṣe ipinu kan ti awọn si kọ iwe si awọn alamojuto eto Ijọba Apapọṣe ni Eko wipe awọn fẹ ki Ijọba gbe ofin kan jade wipe ẹnikẹni ninu awọn obi ko gbọdọ gba owo-idana mọ lori awọn ọmọ wọn obinrin.

Ẹniti o ṣe alaga ajọ ipade na ni Iyaafin Funmilayọ Ransome-Kuti tiṣe iya-ẹgbẹ fun gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Apapọṣe awọn obinrin nwọnyi, awọn obinrin pataki pataki si kun ipade na. Ọjọ meji gbako ni nwọn fi ṣe ipade ajọ nla na ninu ile ti nwọn nfi awọn nkan han ni Ẹhingbẹti l'Eko.

**Iyaafin Ransome Kuti k awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ pupọ ninu irohin ti o ṣe fun awọn ọmọ ẹgbẹ na, o ni iṣe mbẹ niwaju awọn pupọ lori ọrọ nkan ti o jẹ mọ nkan awọn obinrin. Iya-ẹgbẹ Ransome-Kuti tun fi ye gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na wipe agba ṣẹ nde si on nitorina on fẹ ẹniti yio ni akikanju bi on lati ma ṣe asiwaju fun wọn.**

Ẹniti o tun sọrọ ninu awọn obinrin pataki ti o tun wa nibẹ ni Ọlọla (Lady) Kofo Ademọla. O ni bi awọn ko ba fẹ tan ara awọn jẹ, o ye ki gbogbo obinrin ti o ba ti di iyawo nile ọkunrin ma lọ fi oruko sile ninu iwe-igbeyawo lọdọ Ijọba.

Ọlọla aya Ademọla ni irufẹ iforukọ silẹ bẹyi ni ipe lagbaja ni o gbe mi ni iyawo ko ni jẹ ki ọkunrin na raye fiya jẹ ọmọbinrin ti o ba gbe niyawo sile mọ. Iya orisirisi pọ ti awọn ọkunrin aiye ode isisiyi fi njẹ obinrin.

Ki nwọn to mu apejọ ipade ẹgbẹ awọn obinrin na wa si ipari, gbogbo wọn ni nwọn fenu sọkan wipe awọn rẹ ki Olotu Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni Oke Ọya, Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello, Sardauna Sokoto ṣe ofin lati yọnda fun gbogbo awọn obinrin Oke Ọya lati le ma dibo gẹgẹbi awọn obinrin ẹgbẹ wọn ni Ipinlẹ Iwọ Orun ati Ila Orun.

## AKIYESI

**E ka irohin Ayiluka Eleti–Ofe ni oju ewe karun fun omitoro oro lori ipade nla ti awon obinrin nwonyi se ati awon nkan miran.**


*YOUR SPECIALIST FOR ALL*

BUILDING MATERIALS

**BROSSETTE (NIGERIA) LTD.**

WHARF ROAD – APAPA – (NIGERIA)
P.M.B 1135 – APAPA.

*At your service*

- STOCK
- SPECIAL ORDERS
- TECHNICAL INFORMATIONS

S :-

# Nigerian Women To Tour Britain

n Nigerian women set off n the first stage of their s guests of the British

ides Ministers' wives and introductory course in y will study local govern- elfare. The rest of their ng how people in Britain work. To do this they tories, hospitals and wo- In Manchester they will lice force.

Education; Malam Aishan- tu Hajiya, wife of the Nothern Minisiter of Finance; Miss Barik-su Mohammed, a nurse, Mallam Amina Ibrahim, a teacher sponsored by Sokoto N.A. Miss Naomi Timothy, a teacher at S.I.I., Kwoi, Mrs Mariyamu Dinka, wife of District Superintendent of Police, Niger Police Force Force Zaria Province;

Mrs. Ayo Eduu, a midwife of Ilorin N.A.; Mallama Falmata Mani Matron of the girls' secondry school Maiduguri Mrs. Grace Amego, a Social wealfare officer Isala, N.A. and Mrs Agnes Ebun Ajayi, midwife, of Kabba Native Authority.

**Read And Advertise In Eleti-Ofe**

## British Aviution Leads

LONDON — The British aircraft and aviation industry led the world, Mr. Julian Armery, Minister of Aviation said yesterday speaking at Stoke-on-Trent, in the English Midlands.

Mr. Amery, who goes to Russia today, said there was nothing on the other side of the Atlantic or in Russia to compare with the British aviation industry, which was producing a passenger aircraft which could cross the Atlantic in in three-and-half hours. There seemed, he said, no prospect of anyone else having an aircraft like it.

Another marvellous development was a blind landing device, which new British airliners would have built into them— the first aircraft in the world to have it.

Mr. Amery said Britain was also embarking on a method of space communication which would enable people in Britain to talk to Australia and Canada and remote parts of the world by way of satellites.

"We think we shall have the capacity for doing this by the end of the decade," he said.

## Nigerians Study Government Finance

LONDON—Two Northern Nigerian local council officials in Britain, Mallam Garba Kangiwa, Senior Councillor of Argungu N. A. and Mohammed Kukuwa, Secretary to Bornu N. A. Council, Maiduguri, are nearing the end of a year's study trip made under the Nigeria/U.K technical assistance arrangements.

Recently they have been studying the system of Government finanical assistance for families wanting to buy their own homes.

This system was found generally throughout local authorities in Britain and was widely used by families especially young couples, seeking homes of their own, said Mallam Garba.

The two officials have made a detailed study of public and social administration in England at the South Devon Technical College in Torquay. Their studies have included all forms of local government from village to central levels.

"I have also been making weekly visits to various farms and farming institutions in the neighbourhood while at Torquay," said Mallam Garba. "At home our farmers concentrate on crops but in Britain mixed farming is carried on very successfully and I should like to see it introduced in Northern Nigeria."


**CARSON PAINTS AND VANISHES**




SOLE AGENTS:

IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, Balogun Street, Lagos



BA NWÁ
NRA RẸ"



wà ninu mọto



RCLAYS
BANK
D.C.O.

## Loya Igbomina Kinni Di Omo Egbe Olomi

(O [illegible] ẹ loju ewe kinni)

iwuri nipa ire ilu ti on ti ngbọ wipe olori ẹgbẹ na ati awọn ọmọ ẹhin rẹ nṣe fun gbogbo agbegbe ilu ti o wa ni Ipinlẹ Ijọba Ariwa. O ni on kan saara si Ọlọla SardaunaSokoto tiṣe Olotu Ipinlẹ na fun iru iwa bayi.

Onirohin Elet -Ọfẹ ni on gbọ wipe ni Eko ni lọya tuntun yi yio fi ijoko iṣẹ rẹ si ati pe awọn ọdọ ọmọ ẸGBẸ OLOMI (NPC) na ti yan an ni oloye oludamọran lori nkan ti o ba jẹ mọ ofin fun wọn ni agbegbe Ilọrin kakiri.

## Iya Kan Sin Omo Re Laye

(O bẹrẹ loju ewe kin

Irohin ti a gbọ nipa ọm ilewe na ni pe ni ile awọ agbẹbi ọmọ ni o bi ọmọ n si, o si ṣe to ọjọ mọkanl ; nibẹ ki nwọn to wipe ki o ma gbe ọmọ rẹ lọ si ọdọ bi rẹ. Bi ọ ti de ibikan ni ya sinu igbo, osi wa ilẹ, sin ọmọ na si loyẹ.

Nigbati o dẹ ilẹ, o sọ fun iya ti o bi wipẹ ọmọ ti on bi ti ku awọn agbẹbi si ti ba on sin in. Lọjọ na ti iya de bẹ lati dupẹ lọwọ awọn agbẹbi fun oku ọmọ ọmọ on ti nwọn ba on sin ni o gbọ kulẹkulẹ ọrọ na.

Nigbati ọwọ awọn ọlọpa tẹ ọmọ na, o jẹwọ, o si fi ibiti o gbe sin ọmọ rẹ na si ni aye han wọn ninu igbo.

# Alhaji Adegbenro Jare Apakan

(O bẹrẹ loju ewe ki ni)

Eleyi jẹ ki nwọn tun ru ẹjọ na wa si kotu - nla l'Eko, adajọ-agba ti Eko tun da O ye Akintọla na lare. [illegible] eyini Alhaji Ad [illegible] uro ba fi sọ wipe a [illegible] bi on ba gbe ẹjọ yi lọ ba awọn ogunna gbongbo adajọ ilu Oyinbo ki nwọn yanju rẹ fun awọn.

Ni owurọ ọjọ Aje kanna ti nwọn ṣe idajọ yi ni awọn ọmọ ile Igbimọ Asofin fọwọ si iwe-ofin tuntun kan wipe Gomina Ipinlẹ na ko ni agbara kan mọ lati yọ Olotu I [illegible] ba, a fi bi o ba gbọ daju lati ẹnu awọn ọmọ ile Igbim [illegible] wipe aw [illegible] ko ni gbẹkẹle [illegible] rẹ [illegible] o: Tafawa [illegible] Ijọba Apapọṣe tẹle ti o fi fi gẹgẹ le ọrọ na loru ana l'Eko wipe Ijọba apapọṣe ko ri nkankan ṣe si ọrọ na ju wipe ki awọn faramọ atunṣe ofin ti awọn ile Igbimọ aṣofin Ipinlẹ na gbe jade lọ. Ọlọla Tafawa Balewa ni on si ti gbọ wipe awọn Igbimọ si ti wipe awọn faramọ iṣẹ Oloye Akintọla gẹgẹbi Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun.

Ayiluka oniroh n Eel ti Ọfẹ ni on ti gbọ w i p Ọlọla Tafawa Balewa tẹ sọ fun akọwe agba Ilẹ Igbimọ aṣofin ti Ijọba Apapọṣe wipe ki o tẹ waya si gbogbo awọn ikọ ọmọ ile Igbimọ na ki nwọn de si Eko fun ipade pataki kan.

Nwọn ni nkan ti nwọn pe ipade pajawiri yi si ko ye awọn, ṣugbọn O da mi loju gbangba wipe nipa idajọ Ọrọ Kotu Kotẹmilọrun ti Alhaji Adegbenro ati ti Oloye Akintọla ni nwọn fẹ sọ nibẹ.

Ṣugbọn sibẹ sibẹ Oloye Adegbenro ti pe Ijọba Iwọ Orun lẹjọ lori ofin atunṣe ti o sọ wipe nwọn ṣe ni pajawiri.

NEW NOW AVAILABLE

THIRFTY NIFTY

'HONDA 50'

C 240
£64

ALSO

| | | |
|---|---|---|
| C100 | 49cc | £80 |
| C102 | 49cc | £90 |
| C114 | 49cc | £85 |
| BENLY | 125cc | £150 |
| DREAM | 250cc | £198 |
| DREAM | 305cc | £210 |

250 MILES PER GALLON



NEW WORD FOR FUN ...HONDA

ALL 4-STROKE MODELS NO MORE MIXING PETROL WITH OIL NO WORRIES ! !

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (EB) IBADAN — KANO — KADUNA — JOS — P. HARCOURT — ABA

## Ategun Buruku Pa Enia N'India

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Irohin ti a tun gbọ lati India nipa ofo ti at gun alanjannu yi ṣe gbogbo awọn ilu ti o kọlu pọ ju eyiti a le fẹnu kan lọ. Ọgbẹni Ayub Khan tiṣe balẹ ilu na ni Ijọba awọn ti fi owo iyebiye kan silẹ lati fiṣe iranlọwọ fun gbogbo awọn ti atẹgun nla na sọ di ẹdun arin lẹnile ati lcko.

P [illegible] ted and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos, Phone 23370; Editor, (Olotu) Ola, Onatade, 15, KosọkọStreet, Box 467, Lagos.